# IWA-MIMỌ́ NINU AYE ISISINYII

## Johannu 17:21-23; Galatia 5:22, 23; Efesu 4:17-32; 5:25-27; Kolosse 3:1-15; Titu 2:11-14

## ẸKỌ 263 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ mã lepa alafia pẹlu enia gbogbo, ati ìwa mimọ́, li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa" (Heberu 12:14).**

**Igbesi-ayé Titun**

Ninu ẹkọ yii a n kọ nipa igbesi-aye Onigbagbọ. Nigba ti eniyan ba ri igbala, yoo maa gbe igbesi-aye titun. Aye rẹ̀ ti yipada kò si tun gbé iru igbesi-aye ti o ti n gbe tẹlẹ ki o to ri igbala. Oun kii ṣe bi awọn ti kò mọ Ọlọrun. Oun kii ṣe bi awọn ẹlẹṣẹ ti n ṣe. Ọlọrun sọ fun awọn Ọmọ Israẹli pe wọn o jẹ "iṣura .. jú gbogbo enia lọ" fun Oun bi wọn ba gbọran si aṣẹ Oun (Ẹksodu 19:5). Jesu n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ jẹ "ini on tikalarẹ, awọn onitara iṣẹ rere" (Titu 2:14).

Onigbagbọ kò tun si ninu ẹ̀ṣẹ mọ́, ṣugbọn o wà "ninu Kristi ...ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i nwọn si di titun" (2 Kọrinti 5:17). Nigba ti eniyan bá ri igbala, a dari awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i, a o si mu wọn kuro ninu ayé rẹ̀. Bi o ti n gbadura ti o si ṣe ifararubọ aye rẹ̀, Oluwa yoo sọ ọ di mimọ́. A ti kọ́ nipa isọdi-mimọ ninu Ẹkọ 232 ati 238. Jesu gbadura bayii fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀: "Sọ wọn di mimọ́ ninu otitọ: otitọ li ọ̀rọ rẹ" (Johannu 17:17). Jesu gbadura pe ki iṣọkan ki o wà laaarin awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ (Johannu 17:21). Isọdi-mimọ ni o n mu iṣọkan pipe ati wiwà ni ọkàn kan yii wá. Awọn eniyan ti a sọ di mimọ a maa wà ni imọ̀ kan. A ti ṣe apejuwe rẹ̀ pe igbala dabi igba ti a ba ge igi lulẹ, isọdi-mimọ si dabi fifa kukute ati gbonbo rẹ̀ tu. Siwaju sii, apejuwe miiran fi han pe nigba ti a ba gba eniyan là, a kan ẹda ẹ̀ṣẹ -- "ogbologbo ọkunrin ni" -- mọ Agbelebu, ṣugbọn nigba ti a ba sọ ọ di mimọ "ogbologbo ọkunrin ni" yoo kú. Nigba ti Paulu n kọwe si awọn ara Efesu, o gbà wọn niyanju lati bọ́ "ogbologbo ọkunrin ni" silẹ ati gbogbo iwa atijọ ki wọn si gbé "ọkunrin titun nì wọ̀, eyiti a dá nipa ti Ọlọrun li ododo ati li iwa mimọ́ otitọ́" (Efesu 4:22-24).

Paulu kọwe si awọn ara Kolosse pe nipa gbigbe "ọkunrin titun nì" wọ̀, ọmọ-ẹyin Kristi yoo ni aworan Ọlọrun ẹni ti o dá a (Kolosse 3:10). Yoo maa ronu awọn nnkan ti o wà loke, kìi ṣe awọn nnkan ini aye yii (Kolosse 3:2). Awọn nnkan ti ẹmi ni akọkọ ni igbesi-aye rẹ̀, ki o to kan ohun ti ara. Alaafia Ọlọrun ni n ṣakoso ọkàn rẹ̀, ifẹ si wà ninu ọ̀kan rẹ̀ pẹlu "ti iṣe àmure iwa pipé" (Kolosse 3:14, 15). Ami kan ti a fi le mọ pe ẹni kan jẹ ọmọ-ẹyin Jesu ní níní ifẹ si awọn Onigbagbọ iyokù, nitori pe Bibeli sọ fun wa bayii: "Nipa eyi ni gbogbo enia yio fi mọ̀ pe, ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nigbati ẹnyin ba ni ifẹ si ọmọnikeji nyin" (Johannu 13:35).

Lẹyin níní ifẹ lọkàn, awọn oore-ọfẹ Onigbagbọ miiran yoo tun pẹlu. Ninu awọn "eso Ẹmi" ni "ayọ̀, alafia, ipamọra, iwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, iwa tutù, ati ikora-ẹni-nijanu", awọn wọnyi ni o pẹlu ifẹ (Galatia 5:22, 23). A le mọ ẹni ti i ṣe Onigbagbọ nipa igbesi-aye ti o n gbé. "Nipa eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn" (Ka Matteu 7:15-20). Bi eniyan kò ba sọ otitọ, i baa ṣe ọmọde tabi agba, eyi fi han pe kò tii ri igbala ni tootọ, nitori pe Bibeli kọ wa bayii, "Ẹ má si ṣe purọ́ fun ẹnikeji nyin, ẹnyin sa ti bọ́ ogbologbo ọkunrin nì silẹ pẹlu iṣẹ rẹ̀" (Kolosse 3:9). Bi ọ̀kan ninu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ba wi pe oun ti ri igbala, ti o si binu nigba ti kò le tẹ́ ifẹ ọkàn rẹ̀ lọrun, tabi ti o bẹrẹ si sọ ọrọ buburu ati ọrọ irira, iwọ o mọ pe, kò ni igbala mọ, nitori pe Ọrọ Ọlọrun wi pe: "Ṣugbọn nisisiyi, ẹ fi gbogbo wọnyi silẹ pẹlu; ibinu, irunu, arankàn, ọrọ-odi, ati ọrọ itiju kuro li ẹnu nyin" (Kolosse 3:8).

**Jesu, Apẹẹrẹ Wa**

Nigba ti Oluwa ba pe eniyan lati tẹle E, O pè wọn lati "tọ ipasẹ rẹ̀." O pe wọn lati gbe igbesi-aye bi ti Kristi (igbesi-aye Onigbagbọ). Kristi ti fi apẹẹrẹ gbigbe igbesi-aye ti o tọ́ lelẹ fun wa. A kà bayii ninu Bibeli, "Nitori inu eyi li a pè nyin si: nitori Kristi pẹlu jìya fun nyin, o fi apẹrẹ silẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o le mã tọ̀ ipasẹ rẹ̀" (1 Peteru 2:21).

Nigba ti Kristi n gbe ni aye yii, a dan An wò ni gbogbo ọ̀na ti a gba fi n dan wa wò, sibẹ O wà "lailẹ̀ṣẹ" (Heberu 4:15). Apẹẹrẹ igbesi-aye Onigbagbọ ti O gbe jẹ igbesi-aye ailẹṣẹ. Bi a ba tẹle ipasẹ Rẹ̀, a o gbé igbesi-aye wa bi Jesu ti fẹ ki a gbé.

**Agbara lati Pa Ni Mọ**

Nitori pe Jesu bori idanwo, O le ran wa lọwọ nigba ti a ba n dan wa wò (Heberu 2:18). Oluwa ti ṣeleri lati ṣe "ọna atiyọ" ninu idanwo ki a ba le dojuja kọ ẹ̀ṣẹ (1 Kọrinti 10:13). A le tẹle apẹẹrẹ igbesi-aye ailẹṣẹ Rẹ̀ nipa gbigbadura ati wiwo Oluwa ti O lagbara lati pa wa mọ́ kuro ninu ikọṣẹ̀ (Juda 20-24). Peteru wi pe awọn ti a gbala ni a "npamọ́ nipa agbara Ọlọrun nipa igbagbọ́ si igbala" (1 Peteru 1:5).

Nipa agbara Ọlọrun ati nipa oore-ọfẹ Rẹ̀ ni a n pa Onigbagbọ mọ́, nitori pe eniyan kò le pa ara rẹ̀ mọ́ nipa agbara oun tikara rẹ̀. Nigba kan ti Satani n yọ Paulu lẹnu, Paulu gbadura. Oluwa dahun bayii, "Ore-ọfẹ mi to fun ọ" (2 Kọrinti 12:8, 9). Nigba ti Satani ba n sọrọ kẹlẹkẹlẹ si ọ leti lati mu ọ lọ dẹṣẹ, tabi nigba ti ẹni kan ba n rọ̀ ọ lati lọ ṣe ohun ti kò tọ, gbadura ki o si ni ki Ọlọrun ran ọ lọwọ lati ṣe ohun ti o dara ni oju Rẹ̀. A ti gbà wa niyanju lati "wá si ibi itẹ ore-ọfẹ pẹlu igboya, ki a le ri ãnu gbà, ki a si ri ọre-ọfẹ lati mã ran-ni-lọwọ ni akoko ti o wọ̀" (Heberu 4:16). Itumọ eyi ni pe a le gbadura lati beere fun iranlọwọ Ọlọrun, Oun yoo si pa wa mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ nigba ti a ba gbọran si aṣẹ Rẹ̀ ti a si gba A gbọ́.

**Ohun ti a ni lati Ṣe**

Afi bi a ba tẹle apẹẹrẹ igbesi-aye Jesu ti a si gbe igbesi-aye iwa-bi-Ọlọrun, lai ṣe eyi a kii ṣe Onigbagbọ. Jesu wi pe, "Ẹnikẹni ti kò ba rù agbelebu rẹ̀, **ki o si ma tọ̀ mi lẹhin**, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi" (Luku 14:27). Awọn miiran le wi pe kò ṣe e ṣe lati gbe igbesi-aye iwa-bi-Ọlọrun. Awọn miiran si le wi pe o dara fun awọn diẹ lati gbe igbesi-aye ailẹṣẹ -- ṣugbọn pe kii ṣe ọranyan fun gbogbo Onigbagbọ lati gbe igbesi-aye mimọ́. Ṣugbọn bi a ti n yẹ Ọrọ Ọlọrun wò, a rii pe **gbogbo** awọn ti wọn jẹwọ pe wọn fẹran Kristi a maa gbe igbesi-aye aileeri, ti ododo, iwa-bi-Ọlọrun, bi kò ba ri bẹẹ wọn kii ṣe Onigbagbọ. A ti pese oore-ọfẹ ati agbara ti awọn Onigbagbọ n fẹ lati ran wọn lọwọ lati gbe iru igbesi-aye yii silẹ, Ọlọrun si n beere pe ki wọn gbe igbesi-aye wọn bẹẹ. A kò le ṣe ọmọ-ẹyin bi a kò ba tẹle Jesu. Kii ṣe ti Onigbagbọ lati yàn bi oun yoo gbe igbesi-aye iwa-bi-Ọlọrun tabi bẹẹ kọ. Ni tootọ, eniyan le yàn lati jẹ́ Onigbagbọ tabi lati jẹ́ ẹlẹṣẹ. Ṣugbọn Oluwa ti fi ofin lelẹ fun gbigbe igbesi-aye Onigbagbọ, O si maa n fun ni lagbara lati gbe bẹẹ gẹgẹ. A ni lati pa awọn ofin wọnyi mọ́ bi a ba jẹ́ Onigbagbọ.

**Ẹ̀ṣẹ mu Iyapa Wa**

Bi eniyan ba ru ofin Ọlọrun, yoo jiya. Nigba ti Adamu ọkunrin kinni, ṣaigbọran si ofin kinni ti Ọlọrun fi fun un, Adamu dẹṣẹ o si kú ikú ẹmí. Ibẹru ti idalẹbi wọ̀ inu ọkàn rẹ̀ o si fi ara rẹ̀ pamọ nigba ti o "gbọ́ ohùn OLUWA Ọlọrun, o nrin ninu ọgbà ni itura ọjọ́" (Gẹnẹsisi 3:8). Ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti yà a kuro lọdọ Ọlọrun. Adamu kò tun le wà ninu ọgba Edẹni mọ "lati ma ro ó, ati lati ma ṣọ́ ọ," bẹẹ ni kò si le ba Oluwa rin ki o si ba A sọrọ mọ́.

**Igbọran ati Ibukun**

Lẹyin eyi, Ọlọrun fi Ofin fun awọn Ọmọ Israẹli nipasẹ Mose alakòóso wọn. A sọ ohun ti wọn ni lati ṣe ati ohun ti wọn kò gbọdọ ṣe fun wọn. Bi awọn Ọmọ Israẹli ba n fẹ ki aabo, iranlọwọ, ati ileri Ọlọrun jẹ ini wọn, wọn ni lati gbọran si aṣẹ Rẹ̀. Nigba ti wọn ba gbọran, Ọlọrun maa n wà pẹlu won, wọn a si ṣe rere. Nigba ti wọn ba ṣaigbọran, Ọlọrun yoo fi wọn silẹ, wọn a si jiya fun ẹ̀ṣẹ wọn. A kà ninu Majẹmu Lailai nipa awọn ibukun ti awọn Ọmọ Israẹli ri gbà nigba ti wọn gbọran si aṣẹ Ọlọrun, a si tun kà nipa ìyà ati ibanujẹ ti o ba wọn nigba ti Ọlọrun kọ̀ wọn silẹ nitori aigbọran wọn.

Ninu Majẹmu Titun, Jesu fun wa ni ofin fun igbesi-aye Onigbagbọ nipa apẹẹrẹ Oun tikara Rẹ̀, ẹkọ Rẹ̀, ati nipa ẹkọ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ti o ti ipasẹ imisi Ẹmi-Mimọ wá. Bẹẹ ni a n ri apẹẹrẹ igbesi-aye ododo ninu ayé awọn Onigbagbọ tootọ lonii. Awọn ti o ti dan Ọrọ Ọlọrun wò ti rii pe o ṣe e ṣe ati pe awọn paapaa n gbe igbesi-aye ti o bá ilana Ọlọrun mu nipa agbara Ọlọrun. A **le** gbé igbesi-aye bii ti Kristi nipa oore-ọfẹ Ọlọrun. A **gbọdọ** gbe igbesi-aye wa bẹẹ bi a ba jẹ́ Onigbagbọ. Kiki awọn Onigbagbọ ni yoo wọ Ọrun ti wọn yoo ri Oluwa ti wọn yoo si maa ba A gbé.

**Iṣọkan**

Jesu gbadura pe ki a so awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pọ ṣọkan ninu ìdìpọ̀ ifẹ. A so awọn Onigbagbọ pọ̀ pẹlu ara wọn, a si dà wọn pọ gẹgẹ bi ara kan pẹlu Ọlọrun ati Ọmọ Rẹ̀. Jesu wi pe "Ọ̀kan li emi ati Baba mi jasi" (Johannu 10:30). Ilana ati ifẹ Ọlọrun ni pe ki awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ -- awọn Onigbagbọ -- jẹ ọ̀kan pẹlu Ọlọrun ati Ọmọ Rẹ̀ (Johannu 17:21). Wọn ni lati ni ipinnu ati ilepa kan naa, ifẹ ati adura kan naa, kikọ ihà kan naa si ẹ̀ṣẹ, ati ifẹ kan naa fun iwa otitọ.

Iṣọkan wọn jẹ ẹri – "ki aiye ki o le gbagbọ́" ati pe "ki aiye ki o le mọ̀." Bi igbesi-aye Onigbagbọ kò ba yatọ si ti ẹnikẹni, bawo ni aye ti ṣe le mọ̀ pe Jesu n gbe inu rẹ̀, ati pe Kristi ni agbara lati gba ni la kuro ninu ẹ̀ṣẹ?

Ẹnikẹni ti kò ba gbe igbesi-aye ododo kò le jẹ ọ̀kan pẹlu Ọlọrun ati Ọmọ Rẹ̀. "Gbogbo ẹniti nṣe aiṣododo, irira ni si OLUWA Ọlọrun rẹ" (Deuteronomi 25:16). "Bẽni ibi kò le ba ọ gbe" (Orin Dafidi 5:4). Bi ẹ̀ṣẹ ati aigbọran ba wọ inu igbesi-aye Onigbagbọ, oun kò tun ni le gbadun iṣọkan ti o so o pọ mọ́ Ọlọrun ati Ọmọ Rẹ̀, Jesu mọ́. Oluwa kò ni inudidun si ẹ̀ṣẹ, ẹ̀ṣẹ a si maa ya eniyan kuro lọdọ Ọlọrun (Isaiah 59:2). Bi eniyan ba dẹṣẹ kò tun si ni irẹpọ pẹlu Oluwa mọ́, nitori pe "ẹniti o ba ndẹṣẹ ti Èṣu ni" (1 Johannu 3:8).

**Ni Aye Isisinyii**

Jesu "fi ara rẹ̀ funni" O si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun awọn eniyan Rẹ̀ -- Ijọ (Efesu 5:25). Jesu ní "ijọ ti o li ogo li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi irú nkan bawọnni ... mimọ́ ati alaini àbuku" (Efesu 5:27). Ijọ le jẹ mimọ nigba ti awọn eniyan inu rẹ̀ ba jẹ mimọ. Agbara wà ninu Ẹjẹ Jesu lati sọ eniyan di mimọ ati alaileeri, ati lati mu u wà ni mimọ ati alaileeri. Jobu, eniyan Ọlọrun wi pe, "Olododo pẹlu yio di ọ̀na rẹ̀ mu, ati ọlọwọ́ mimọ́ yio ma lera siwaju" (Jobu 17:9).

Bibeli kọ́ wa pe a ni lati gbe igbesi-aye mimọ nihinyii bi a ba fẹ jẹ ọ̀kan ninu Ijọ Kristi, bi a ba si n fẹ lọ si Ọrun. "Ore-ọfẹ Ọlọrun ti nmu igbala fun gbogbo enia wá" ni o tun n kọ́ wa pe, "ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ aiye, ki a si mã wà li airekọja, li ododo, ati ni iwa-bi-Ọlọrun ni aiye isisiyi" (Titu 2:11, 12).

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni o n mu ki eniyan gbe igbesi-aye ti o yatọ lẹyin ti o ba ti ri igbala?
2. Ki ni "eso Ẹmi"?
3. Ta ni apẹẹrẹ igbesi-aye Onigbagbọ fun wa?
4. Bawo ni Onigbagbọ ti ṣe le jẹri nipa Jesu fun ayé?
5. Ki ni itumọ "Onigbagbọ"?
6. Oore-ọfẹ tani o to lati ran wa lọwọ ni igba ti a n fẹ iranlọwọ?
7. Ki ni itumọ jijẹ "ọ̀kan" pẹlu Ọlọrun Baba ati Jesu, Ọmọ Rẹ̀?
8. Pari ọrọ yii "Ẹniti o ba n dẹṣẹ ti ..."
9. Iru awọn eniyan wo ni Jesu ni ninu Ijọ Rẹ̀?
10. Nigba wo ati nibo ni awọn Onigbagbọ ti n gbe igbesi-aye mimọ́ ati alaileeri?